# AGBARA OGUNPA J'OMOGBA LOWO OLOMO




ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI LEJO




VOL. No. IX 513. ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 30, 1957 KOBO MEJI (2d)

## Agbara Ogunpa J'omogba Lowo Olomu

IBADAN. Agbara Kudẹti ṣe bẹbẹ nijo ti ojo bẹbẹ rọ ilu Ibadan ni ogunjọ oṣu ti o kọja yi. Ojo yi bẹrẹ ni aago meje alẹ pelu atẹgun lile lile. Ere ni awada ni, igi ọdan nsun, buka ọja ndọbalẹ gbọrọgbọ.

Ere ni awada ni, ile ori-oke petẹsi dilẹ, ylnyin bẹrẹsi bọ lu ile. Omi ọpọn ti rere, o da bi ẹnipe a fi obẹ ya ọjo ọrun ni. Ṣaṣa ni ile ti omi ko ya si-ṣaga si nile ti ko yọ panu rẹ.

Awọn KORA (Syrians) Gbagi papa fi ara gba ninu rẹ gbogbo aṣọ ti wo nta lọ di tutu.

"Ọlọrun ma jẹ ki a ṣe ofo ẹmi", bi ti ọjọ yi kọ. Baba-aṣọta (night watchman) ti o nṣọ ile awọn oyinbo Ollivant ni panu ti atẹgun gbe wọ laya ti o pa de ọrun. Obinrin kan ti o nṣọ oja Dugbẹ, ni agbara Ogunpa ja ọmọ gba lọwọ rẹ ti o ta okoto rẹ lọ si Kudẹti. A ko le fẹnu sọ iye ti agbara Gẹgẹ ati Kudẹti gbe lọ.

Ninu awọn ile ti o wo ni Mọkola ni Ogbeni Igbodaro ati ẹni bẹbẹ wa. Ile nlọ bi irinwo ti o si fila lori rẹ.

Ọjọ na wa dabi ọjọ ti ẹkun ja nilu Eko ninu ọdun 1913 ti ọlọmọ ko mọ ọmọ, olukulu ndu ori ara rẹ ni. Bẹgẹgẹ ni ọjọ Ojo jamba yi ri nile Ibadan.

Lọwọ jamba nla ati kekere, Oluwa rere gba wa.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubumni Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Milton A Macaulay



Ogbeni Milton Macaulay ti a nwo aworan re ninu iwe wa yi, je onise Ayafoto nile Nigeria, eniti o ti gba oye M.R.P.S., lo mbe lori irin ajo kakiri ile Amerika lati fi iru enia ti awa ara ile Nigeria je han araiye. Ninu irin ajo re, o fi aworan han awon ara ile Amerika gegebi iru asa ti a ni, irisi wa, ati imura wa. Nigbati o ba pari ise gegebi a ti se nfun aworan ni awo tan, yio pada wa sile ninu osu ti o mbo.

### ỌRẸ DIẸ ỌTA DIẸ LO NPA'NIA

Ni igba kan awọn ọrẹ meji kan wa, oruko ekini a ma jẹ Ṣe-dada, ekeji a si ma jẹ Kọtun wọn jijọ da owo pọ wọn jọ fi nṣiṣẹ.

Ṣugbọn Kọtun jẹ oniṣẹ a ṣola, bi Ṣe-dada ṣe fẹran rẹ, ko fẹran Ṣe-dada igbakugba lo si nwa ọna ipalara fun. Ki o ba le je ogun iyen mọ ire. Ṣugbọn gbogbo ọna ti o ngba ni Ọlọrun ngbe Ṣe-dada lekẹ rẹ.

Ni ọjọ kan, o rọnṣẹ si Ṣe-dada po on fẹ jẹ nkan kan, tofina ki o wa ba on jẹ nkan. Ni ọjọ ti a nje nkan na, wọn njẹ onje, ẹrọ gbogbo ọna pe sibẹ o ni ki wọn ba onjẹ fun

(Wo yeku iloju ewe keje)

# Awon Ti Ilekun Ile-we Thomas College

Ibadan -Awon enia kan lo kowe si olotu ile eko (Minister of Education) wipe ilewe kan ti nwon npe ni Thomas Memorial College, ko ni awon ohun elo lowo to fun eko awon omode ti a ni lati ma pee ni College. Asi gbo wipe Olotu ile eko na ko gba pe ki a da ilewe College na duro, awon enia na gbe ejo na lo si kotu niwaju adajo agba.

Lojo ti nwon fe se idaje na, awon omo ile eko Thomas Memorial College bi iwon adota joko ninu kotu lojo na, Olotu ile eko papaa wa ninu ile ejo lojo na.

Adajo agba fi ase si wipe, ki ilewe giga kan to le je ilewe rara, ohun gbogbo ti ni lati peju ninu re gegebi awon ohun elo ti a fi ndan nkan wo (experiment) ati Science (ogbon inu ati ogbon ori) Chemistry ati awon ohun elo bawonni, Sugbon nisisiyi, ko si gbogbo iru awon ohun elo bawonyi. Nitorina o n pa ase wipe ki a tilekun ilewe na titi ti awon ohun elo na gbogbo yio fi pe.

# Iye awon enia ti o jebi iku lodun 1954 - 1956

Okan ninu awon ibere pataki ti nwon bere ninu ile igbimo nla (House of Representatives) nilu Eko ni wipe, enia melo lo jebi iku nile Nigeria larin odun 1954, 55 & 56. Bayi ni nwon ti so se siro awon enia ti a da ijebi iku na.

Ni odun 1934, Nile agbegbe Ila orun enia medogbon ni a da lebi iku. Enia merindinlogun nilu Eko, enia merinla nile Hausa. Ko si enikan ti a da lebi iku ni agbegbe Iwo Orun ati ni Kameru.

Lodun 1955 l'agbegbe Ila Orun enia merindilogoji lo jebi iku. Nile Hausa enia mokandielogbon. Nilu Eko, ogun enia, ni agbegbe Iwo Orun ko si enikan ti o jebi iku, ati ni Kameru enia meji. 1956. Ogun enia ni nwon yegi fun ni agbegbe Ila Orun, enia merindilogun nilu Eko, enia meron ni ile Hausa. Ko si enikan ni agbegbe Iwo Orun ati ni agbegbe Kameru.

Iye awon enia ti o padanu emi won lodun 1956 ninu jamba moto, ni agbegbe Ila Orun je ekan-dinlogoje enia, ni agbegbe Iwo Orun enia mejileladojo, nile Hausa ogun enia, ni Kameru enia mejidinlogoji nilu Eko enia mejilelado.

# Amerika Yio Ni Asoju Ni Kano

Larin odun ti a wa yi asoju pupo ni Amerika yio ni lori ile Afrika, so fi okokan si Mogandisu, Somaliland, Abidjan, Ivory Coast, Kampala, Uganda, Yawende, Tananarivo Madagaska, Brazzavile ati ni Kano.

Bi o ba di ibere osu July so bere si fi awon enia si ipo ti a darako na.



# Alade Odunewu

Eniti a nwo yi ni Ogbeni Alade Odunewu, eniti ijoba ran lo fun lositwaju eko ninu ise iwe Irohin. On lo ti nse Olotu iwe irohin kan ti nwon npe ni Daily Service ri.

Lehin ti o ba ti so osu mefa pelu iwe irohin kan ti nwon npe Worthing Herald, yio tun koja lo kose ni ile ise iwe irohin miran ti nwon npe ni London Polytechnic,

Ogbeni Odunewu yi je odomode ti o ni akinkanju ninu ise re bi onise iwe irohin, eyi l'o mu ijoba apapo (Federal Government) fun ni anfani eko-ofe nilu Oyinbo.


M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sùré, òyì pòṣèṣè. Àlá búburú wọ'gbó. Àìlèsùn rẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. lògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkàn, amú ni yàgbẹ́ bi ọ̀kùn, amú ni tọ̀ bi òkèrè. Abiwéré f'áboyún, agbẹ̀jẹ̀dí f'awọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, èsè-wíwú ati àiyà-jíjá ko sí fẹ́niti nlo o.
4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.
ARADAN STORES P.O.Box 2
EBUTE-METTA.

# Osanyin, Ifa, Alufa danra wo

Lati ọwọ ESO

Lasiko kan sile Iwo, awọn Olọsanyin sfẹ l'i han wipe awọn lo ni alye, awọn Babalawo papas ko kerẹ, awọn Alufa si nse wipe ko si ẹsin miran ti o tun gba iwaju lọwọ ẹsin Imale. Bi ekinni ti nfa ọrọ yi, bẹni ekeji nfa a, ati eketa pelu. Ọrọ yi di akitiyan tobẹ sọ ti ijagboto fi ni lati bẹ silẹ larin awọn mẹtẹta tobẹ ti o jẹ pe, awọn ẹniti ko mọ ọwọ-mọ ẹsẹ le nfi ara korin ọrọ na.

Oluwo ranṣẹ pe awọn Igbimọ rẹ o si bere lọwọ wọn, kini ohun ti o tọ lati ṣe nipa ọrọ yi, ti alafia yio fi wa ni ilu, awọn igbimọ si dahun pe nṣe ni ki ọba dibo fun wọn. Ọba ranṣẹ lọ ra odidi ori malu pupa kan ti on ti Iwo ori rẹ mejeji o si ri i mọlẹ larin afin ọba, o wa ranṣẹ pe awọn Ọlọsanyin, awọn Onifa ati awọn Alufa Imale jọ. Olukuluku wọn de, awọn si joko lọtọlọ, awọn Ijoye ilu ati Igbimọ ti joko si ipo wọn, Oluwo papaa si ganwa sori itẹ.

Ọba Oluwo dahun wipe, gbogbo akitiyan ti ẹnyin ṣọ mẹtẹta yi ti nfa mọ ara nyin lọwọ si mọ ti gbo. Nitorina mo fi ohun kan mọlẹ ninu afin mi yi, ẹnikẹni ti o ba mọ nkan na ni yio je olori nilu Iwo.

Awọn Ọlọsanyin gbe Ọsanyin jade, o si bere si wipe, nkan ẹlẹjẹ lọrun ni nkan na, o si lese merin. Orje korko bi eran, kokoro si wa lara rẹ.

Awọn Babalawo da Ikin, Opẹle, Ipọrin Agidigba. Erindilogun ati Erin ọrọ kanna ni gbogbo wọn sọ (Irẹtẹ kan) Ifa dahun pe ohun ẹlẹsẹ mẹrin ni nkan na, o l'ọmu kan, o ni iwo gagara meji, o si ni awọ pupa, o nje koriko, kokoro ẹgbọn a nsa wa lara rẹ, o wo bata ẹsẹ, o si la ẹsẹ, ko nṣe nkan ti o le yara rin rara.

Awọn Ijoye ti bẹrẹ si fi ẹnu ko ẹnu wipe awọn Onifa ti mọ nkan na ki awọn mase tun bere lọwọ awọn alufa. Ṣugọn Lemomu ilu na dahun pe, Irẹ ni awọn Babalawo ko mọ ohun ti o wa ni bẹ awọn yio sọ nkan ti o wa nibẹ nisisiyi. Ọba si fun wọn laye ki awọn sọ ti ẹnu wọn.

Lemomu se asalatu fun Anọbi tan, o wipe ki Ọlọrun gbe suna Anọbi ga, ki o si rẹ Bidia nilẹ ohunkohun ti ọba le ri mọlẹ na, ki Ọlọrun sọ nkan na di adie fatiha. Iyalẹnu lo jẹ fun ọba ati igbimọ nigbati awọn de ibẹ ti awọn si ba adie. Lati ọjọ na wa ni Imale ti fi ẹsẹ mulẹ si Iwo ti awọn si gba Babalawo laye nilu pẹlu.

## Asotele Nipa Ohun Ti A nri

1. Bi enia ba nlọ sibi kan, yala o nlọ si ajo ti oluwa rẹ si ri Ologbo ti o sare da ọna koja niwaju rẹ, eleyi ti o ye arinrin ajo na ni wipe, ki o pada sehin nitori ibiti o nlọ ni, ti yio ṣe l'anfani tabi boya ewu nbẹ niwaju. Sugbọn bi o ba je wipe ologbo dudu ni o ri, ti o si jade lati apa ọtun si osi, osi, ibiti oluwa rẹ nlọ na yio safani. Iyen ni wipe bi o ba pe osi lo ti bẹ si ọtun kodara.
2. Bi enia ba ri ẹta ina ti o ta sọrọ jade lati ara ina abẹla tabi ina ti a tan kalẹ, eyiyi je asọtẹlẹ wipe, oluwa rẹ yio ri Iwe kan gba tabi ki o gbọ irohin laipẹ. Sugbọn bi o ba ri ẹyẹ ina roboto lara owu atupa na, eyi je asọtẹlẹ wipe ifa owo mbọ wa bẹ ẹniti o tan ina na. Bi o ba si sakiyesi wipe ina atupa na di bulu, eyi je ami wipe eranṣi tabi Alijannu kan wa ninu ile na.
3. Bi enia ba kọkọ jade ni owurọ, ti o si pade aja, oluwa rẹ yio ṣe ori-re lati ọdọ ere rẹ.
4. Lasiko ti o nlọ sibi iṣẹ, bi o ba pade ẹran ewure, eyi je asọtẹlẹ po lọhin sara ati ifọriti oluwa rẹ yio je anfani pupọ.

# Awọn Ọmọba Niwonyi



Awọn ti a nwo nihin yi ni awọn ọmọ bibi inu Ọba obinrin Elizabeth keji tile oyinbo ti o bi sori itẹ Ọba. Ọkunrin kan ati obinrin kan, eyi obinrin jẹ nje Anne ọkunrin lo si nje Charles, on lo si ni ẹtọ lati jẹ oye H. R. H. Prince of Wales. Ọmọba Charles yi lo ti goke agba di ọmọ ọdun mejọ ati ọṣu merin nisisiyi.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra OMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun oṣutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o nmu mba ọmode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELLA BABY MIXTURE

(SIBI MEJI ADO ... FUN ... KAN)

O wa lọọyi

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

in VICTORIA STREET, LAGOS





# ELETI OFE

A-NIU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 21, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 447

CABLES & TELEGRAM "ELETI – OFE LAGOS" Phone 23370

VOL IX. NO 513. LAGOS, SATURDAY MARCH, 30 1957


## Egbe Oloko-Ile Gbarada

(RAILWAY CORPORATION)

Ati male lo, awo pada s'ehin ni awon ole meta teo ti awon egbe Oloko-ile tige gbe j'ade ti a npe ni (Restaurant Car) ile onje lorisirisi adidun lori irin ajo fun awon ero ti o ba wo oko-ile (Railway) fun igbadun ti o ni alafia stata ninu.

Awon aga ijoko inu re je eloyibinipo ti o ma nyi si ayekaye legbe tabili onje, bene afefe igbadun yio ma fe ti awon ero ko ni fi ri oye ora rara. Eyi nikan ko, bi o fe onje tutu tabi eyiti o nlo woro-woro, o mbe ni ar'owoto.

A gbo wipe ekeji iru oko ti yi o ti de sugbon kohi jade fun llo ni eyiti owo ti awon fi kan je egbaa mokanla pgun. (£22,000) o wuwo to Toun mokanlelogbon o si gun to esgota ese. Gbogbo ara re, ati inu ati ode je eyiti a se ti kole le da opapa, koro ni gbogbo re ndan.

A gbo wipe Olola-nla Gomina agba ni yio ko si lilo oko na ninu osu April, to mbo ki o to wa di lilo ti gbogbo ero. Koseto ni oko na, awon ohun mimu ati jije, eyiti a nnu okan tutu pese, mbe fun igbadun awon ero oko. Ohun jije ti ile wa bi efo tabi awon eso l'orisirisi ti o ba wa ni ilu Nigeria lara mu mbe l'arowoto pelu.

Awon egbe Oloko – ile gbarada, t'elegan l'oku.

## Idahun Si Ibere Ologbon Ile Oyo

Oletu

Eyi ni Idahun si Ibere Ologbon Ile Oyo ti o jade ninu iwe Irohin yin oloyin momo ni 16. 3. 57.

Ibere Kini – Ewo lo wiwoju ninu epo ati omi, mo si fe ki e se alaye fun wa, Idi re ti okan fi wiwo ju ekeji lo?

Idahun – Emi ro pe omi lowiwo ju epo lo o. Idi re nipe ti a ba da epo sinu omi ase lo ma lefo si oju re, bode jepe omi ni a da sinu epo, omi yen a lo si isale epo a de lefo soke bakanna.

Ibere Keji – Osan mimu meji kan wa (oranges) ti nwon ko tobi ju ara won lo, beni nwon ko wuwo ju ara won lo. Afi obe la okan si ona meji, a si la ekeji si ona 'meta. Ninu awon osan meji yi ewo lo wuwo ju lehin ti a ti laa tan; kini Idi re ti o fi wuwo?

Idahun – Osan ti a la si meji lo wuwo ju o.
Idi re nipe, nigbati a nla lowo omi die ni lati fun jade ninu re. Omi ti o de ni lati fun jade ninu eyiti a la si meta ni lati po die nitoripe nigbati a la si meji omi die yio fun jade nibe lehin ti a tun le ipin keta nibe omi die a si fun jade nibe. Nitori idi eyi ni osan ti a la si meji fi wuwo ju eyi ti a la si meta lo o.

Ibereketa – Ewo lo wuwo ti agbara enia ko le gbe ninu ewe takada kan ati ogulutu kan.

Idahun – emi ro pe takada lo wuwo ti agbara enia ko le gbe o.
Idi re ni pe a le ko akole enlti o ni takada si ara re tabi ki a ko ofin si oke takada pe enikeni ko gbodo mu laigba ase, ako de gbodo fi agbara mu. Takada emiran si nwa toje pe a ko ti ga ti o fe tobi to gbogbo Ibadan ti agbara enia ko si ni le ka lati gbee. Sugbon ogulutu wa nibe ti enikeni le gbe nile ki o si ju nu omode kekere papa le he ogulutu nile ki o si so si ibikibi ti o ba wun.

Abo mi ree o, Oletu, Owo ama roke, Oko Ona ko ni sa yin lese o.

Emi ni

Olabisi Ishola.

E ma polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti - Ofe



## Ribadu Nki Awolowo

Aworan inu iwe wa yi niti Malam Muhamed Ribadu ati Olola Obafemi Awolowo ti ise Alakoso Ijoba Iwo - Orun (Premier) nigbati on pelu Alhadji Ahmadu Sardauna, Sokoto fi dakan lo silu Ibadan lati ri Olola Awolowo lori ipade po se ajohun ki owon to lo silu Oyinbo fun eto Ilu Nigeria (Constitutional Conference).

## Oyinbo Amerika Wa Mo Orisun Baba Re

Irohin kan wa wipe Oyinbo kan ba oko Reluwe gunle silu Ibadan, o wa mbere ile Ọlọni, Station Master ni ki nwọn mu lọ sọdọ awọn Ọlọpa. Lati ibẹ ni awon Ọlọpa ti sin lọ sile Ọlọni ni Ọja oje ni Ibadan.

Nigbati o de ibẹ o ni ki nwọn ba on pe gbogbo awọn ara ile jọ. On papaa joko sori aga, o yọ iwe jade ninu apo, O bere Orodoyin, ko si ẹniti o mọ ẹniti nwọn npe bẹ, a ya fi baba agba kan ti o wa ninu ile ti ko le jade mọ lo dahun pe iyawo ẹniti o tẹ agbole yi lo njẹ bẹ, o wa bẹrẹ si bere oruko awonyi Ọnigbade, o ti ku, Ọnibami, o ti ku Ọnidele o ti ku bẹni o mbere lọ kan-kojọkan.

O wa bẹrẹ si pitan ara re, o wipe, Ornideiay (Ọnidele) ni oruko on njẹ, oruko Baba on ni Ọnigegun, ọtẹ lo tẹ baba on ki o to de ilu Amẹrika, Ọlọrun ṣe adsiki fun lọhun, o si fẹ iyawo on ti o nṣe ọmọ-olowo kan nilẹ Amẹrika ki nwọn to wa bi on. Pẹlu pẹlu gbogbo itan ti on ti npa lati oni wa nṣe ni on ba ninu iwe akọsilẹ.

Ṣugbọn on gẹgẹbi ọmọ wọn nṣe ni on wa mọ ile lelọpẹ on yio pada sile, on yio si rohin pe on ri awọn ẹbi wọn. O ba wọn ya fọto, o si pada si Eko.

## Idahun Si Ibere Dr Jenmi

Olotu,

Gbami laye olotu, ninu iwe re lati dahun si ibere Dr. Jenmi, eyiti o jade ni ọjọ 16th oṣu Feb 1957. Idahun 't e m i niyi wipe. Obinrin kan ko le to fun ọkunrin kan nitoripe awọn ara iṣiwaju ti fi apẹrẹ lelẹ bakanna le si h a n ninu Bibeli.

Ẹniti o ba lewo lọwọ ti o si roye pe, on le kapa awọn obinrin mẹjọ ki on si tẹwọn lọrun, ti awọn na yio si tẹ on lọrun de ipo ti on ko fi ni yọju si nkan ti ẹnikeji tabi ti Aladugbo ee, o le ṣe bẹ. Awọn obinrin ko yatọ si ara wọn bakanna ni nwọn ri, aparo kan ko ga ju ekeji lọ, ayafi eyiti o ba gun ori ebe.

Iba nkan ti obinrin fi ga ju ara wọn lọ ni ẹwa iyẹn ni wipe ẹwa ati Iwa ni nwọn fi dara ju ara wọn lọ. Bi o ba si jẹ wipe, obinrin kanṣoṣo na ni agbara rẹ ka lati fẹ, ko si ẹri tabi ofin ti o daju ti a le fi so pe, e wa bẹ wipe dandan n i k i ọkunrin kan ni obinrin kanṣoṣo.

Nina Iwe Korinti 1 ori 7, ẹsẹ 2-6, nitori agbere, ki olukuluku o ni iyawo tirẹ lọtọtọ. Nitori idi eyi, emi ko faramọ nṣe olobinrin kanṣoṣo.

Emi ni

Lemẹmu Ajakata

ara Eko

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



Read this list of popular titles

JZ 6037—Bo Ba Sorun / Iya Egbe) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.

" 6038—Emi O Se Ola / Konkoji ) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.

" 6052—Kusimilaya I / Yanboss) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.

" 6053 Kilo Se E/Kusimilaya II) Victor Olaiya & His Cool Cats Orchestra.

JZ 6050—The Gentleman in the Wardrobe (The Lady with the Pancake Make-up) Bobby Benson & His Havana Orchestra.

" 6051—Mamma Klapo/Uncle Joe) Bobby Benson & His Havana Orchestra.

" 6048—Erin Folami/Oju Lo Pasi) Adisa Danbawa & His (Apala) Band.

" 6049—Egbe Maaho/Karimu Ajose) Adisa Danbawa & His (Apala) Band.

Sold by all the best stores

"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Owo Oba Te Awon Olosa

... ẹgbẹ ogun Ọlọsa ... kekere kan ... Shaki ... ni Ọyọdele, ... awọn ja ni ebu-... ni awọn pa ara ... kan ti awọn ope ... Shaki, awọn ko ... si salọ.

... awọn Ọṣẹlẹmuyẹ ... ilẹ ni ọwọ ti tẹ ... Ibaruba merin awọn-yi ... Godonu, ... Yebra Huawenu, ... Okekosi, ati ... Ibe awọn ti ... ninu wọn nyen, ... Faranse ni awọn ti ... na wa.

... awọn ọlọpa ti ... ẹjọ ... wọn si de A...

## NWỌN TUN GBE OFIN YI DE O

Nisisiyi ni Okunrin ... kan gbe ọrọ yi ... si igbimọ wipe ki nwọn mu ofin ti wipe kia ma yegi fun enia kuro, awon igbimọ kekere ti ara mọ wipe ... ki nwọn ṣe ... sugbọn awọn igbimọ nla ki-gbe ... kini awọn ... nwọnyi fẹ ... le yi, awọn ko lo ... ara mọ rara, ni awọn ba pa ọrọ na ti.

Eyiti nwọn tun ṣe-ṣe gbe de niyi wipe, iru awọn ọdaran ti a o ma yegi fun niwọn-yi, Ole ti o ba panis, tabi enit o nda awọn elewọn, Ijhin iru awọn ... bawọnyi, gbogbo awọn enit o ba da-... ọjọ ... a o ma fi si ewọn ọdun gbo-ro.

Eyiti nwọn tun ṣe-ṣe gbode niyi, ewo ni ẹ ti wi si eyiyi?




## Idahun Si Ibere Dokita Jenmi

Ọlọtu,

Jọwọ gba mi laye ninu iwe re oloyinmọmọ lati fi idahun si Ibere Dokita Jenmi ti o jade ninu iwe ti 16.2.57.

Idahun temi ni pe obinrin ... ko to fun okunrin kan nitoripe awọn ... ti fi apere lelẹ ninu Bibeli papa.

... bale kapa obinrin ... iyekiye ti yio fi le ... oju kuro lara obinrin ... ọmọnikeji le yẹ ki o ... Ti o ba si le ku ara ... o le fẹ okanṣoṣo.

... pe "Nitori agbere ... o ni aya ... I korinti 7 2.b.

Nitori idi eyi emi ko faramọ ... aya obinrin kan. ... ti o ba si ri eri ti o ... obinrin kan ki o ... gbọ.

Ọlọtu, mo dupẹ aye ti ẹ fun mi.

... A. Gbegbin Sheoko
A.S. & Co.

## Idamu Erin Nile Kamaru

BEUEA Nigbati idamu awon Erin poju ni abule kan ti nwon npe ni Bonakanda nile Kamaru, nwon mu ejo lo sodo Ogbeni E. M. L. Endeley lati rohin iru wahala ti Erin nfi oju won ri. Sugbon nwon ko le ri Ogbeni na ba soro.

Nigbana ni awon ara abule na ba tun ko ejo won, o di odo ajele agba, nwon si rohin fun wipe, idamu ati wahala ti awon Erin nfun won ni abule won ti po, nwon mba awon ohun ogbin won je nwon tuwo abule wa wo ile mo won lori, emi won si wa ninu ewu. Bi ijoba ba fun won lase lati gbogun ti awon eranko nwonyi, ao gba ara wa sile nitoripe bo ni a ti nse pelu won nigba lailai.

Ajele agba na so fun won wipe, on ko le fun won lase lati lo pade ija pelu awon Ajanaku sugbon ohun ti on yio se fun won nisisiyi ni wipe on yio ko awon ohun ija fun awon Olopa lati lo ba awon eranko na koju ija. A si gbo pe losu ti o koja, Ogbeni Endeley pa okan ninu awon Erin ti o nyo won lenu na.

## Awon Olosa lu Okunrin Olola kan

EKO. Lasiko ti awọn nṣe igbimọ lọwọ ni ọkunrin ọlọla kan dide sọrọ bayi wipe, "On fẹ ki ijọba ri si ọrọ pataki ti on fẹ sọ oni yi, ki awọn si sọ fun wa gbọ ewo ni ṣiṣe ni di ọrọ na."

Ọkunrin Ọlọla na sọ wipe, nigbati oun ma on ... mo lọ gba afẹfẹ ni Okun Alasia, lọjọ Jimọ kan, ibẹ ni awọn Onibaranda ati Ọlọṣa gbe ti ki on mọlẹ, awọn si lu on tatu.

Ohun ti o tilẹ dun on nibẹ ni wipe, ni gbogbo asiko ti awọn ole nwọnyi fi nlu on ... nṣe ni on ... ibosi awọn Ọlọpa, bi on ti kerosi to, on fere ṣu bi o tilẹ jẹ wipe ile awọn ọlọpa nbẹ nitosi, sibẹ on ko ri iranlọwọ kan lati ọdọ wọn.

Bi ijọba ko ba mu ogiri si iru ọrọ pataki bayi nijọmiran, awọn le lu enia pa, ki awọn si ju sinu okun. S kiteri agba tilẹ Nigeria sọ fun igbimọ na wipe on yio ba Olori awọn Ọlọpa sọrọ nipa ohun ti o ṣẹlẹ yi, ati pe ki o tun bo ṣiṣẹ si waju, lati fi awọn Ọlọpa sọ eti Okun Alasia.

# Bi obinrin ti se poju okunrin lo

Nipa ibere DR. Jenmi, ti o bere wipe, ewo lo daraju, ninu olobinrin pupo ati olobinrin kan. Gegebi oro na ti lo niyi. Nigbati iwa se, okunrin ni Olorun da sile aiye isedre, sugbon obinrin kan soso ni a da si arin won. Oruko obinrin na a ma je Onisoso.

Lode orun ni obinrin yi ngbe. osu meta-meta lo nwa sile aiye lati wa bimo, osu meta lo fi nloyun. (Ni apẹ c). Bi o ba sokalẹ wa sile siyo ninu osu January, ninu osu na ni yio loyun, yio si bimo ninu osu Feb., yio gbe omo na lo orun ninu osu Feb. na. Nigbati o ba di osu March yio gbe omo na sokalẹ wa yio si tun loyun miran Bayi ni Onisoso nse.

Lasiko ti Onisoso ba wa lode orun ko ni si ija larin araiye ko si ni si owu jije, sugbon nigbati Onisoso ba de, awon enia a ma titori re se ara won ni jamba, nigbati iwa bayi se ndi kasela, awon araiye ran iko si Olodumare wipe, obinrin kansoso ti Olorun nran si aiye yi ko sise rara, ki o ran obinrin pupo si awon Olodumare ranse pada, wipe on gbo sugbon lojo jimo ti o mbo wa, enikan ko gbodo lo si oko. Nigbana awon ara ile Ife gbo, nwon se bi lodo won ni awon obinrin yio sokalẹ si, awon gbo, nwon ko lo oko. Sugbon Elesiẹ oba ilu Esiẹ ti o lu agogo kakiri ilu wipe, Kere o! Olodumare ni awon obinrin yio sokalẹ to araiye wa lojo Jimo, nitorina enikan ko gbodo lo si oko. Elesiẹ gan lo koko ti lo si oko, nitorina bi o ti wio, lo se konge awon enia ti o nsokalẹ lati orun.

Nigbati awon enia na fi oju kan araiye nse 'ai gbogbo awon di okuta, gegebi o ti wa ni Ilu Esiẹ titi di oni. Awon araiye tun ranse si Olodumare pe, awon ko ri awon obinrin na, ati pe ara won si wa lona.

Olodumare wa ranse pe Obatala, wipe ki o mo ere enia ni obinrin, Olodumare se Si-I si won, awon di enia, nwon si sok le si Ile Ife, lati ojo na wa ni obinrin ti dipupo.

Sugbon dipo ki awon obinrin nwonyi ma bimo ni osoosu meta-meta, ododun ni awon mbimo, bi nwon si ti mbimo yi, ejiro ni awon ibi, awon ibeji na si je olobinrin, je olobinrin, agbara kaka ni nwon fi ibi okunrin kokan la a.

Nigbati nwon ti bi obinrin pupo sile aiye tan, Olodumare ni ki nwon ma pada bo lode orun, ile aiye ti dun mo awon obinrin nwonyi tobe ti nwon fi tako ko lati pada sode orun, Iba awon obinrin die lo pada sode orun, nigbana ni Olodumare wa ran Obatala lo sile aiye lati le po awon obinrin yoku wa.

Obatala jade lo, o ri awon obinrin na, o pe won lati pada si orun, nigbati nwon si ko, ni Orisa ba bere si gba eye kokan lara awon obinrin na ati lara omo won. Eyi ni idi re ti nwon se npe Afoju, Aditi Are, Atiro, Odi, Agepa, ati Agese ni Eni Orisa.

Emi ni
Eso Ikoyi

# Abiyamo tu omi gbigbona sara Enia

JOS Obinrin kan ti a npe ni Cecilia ti o bi omo ti o nto lowo, o si dagba to omo odun mejilelogun ni a gbo wipe, o mba Alice omo odun meji yan odi ninu ile, tobe ti awon ko fi nki ara won. Ninu ile kanna ni awon ngbe.

Alice ti o je omode kekere lo bu omi tutu lati fi se nkan omi na si wa sasi kan si iya yi lara (Cecilia). Inu bi Cecilia tobe ge, o mu panu o si fi bu die lara omi gbona ti o gbe ka ina, o si da si Alice lara, nse ni ara re si bo toro.

Adajo ti pe nse ni ara re gbona, o ni ki o lo si ewon osu mefa pelu ise asegan. Eyi fi otito owe Yoruba han, ti o so pe "ibinu ko da nkan, suru baba iwa".

# Ilu Sweden o Ni Eiye Na

Nipa eiye ajeji kan ti a ti se ikede nipa re ni osi wipe, okunrin ode kan ti a npe ni Ugbagu ri eiye asa kan ti o ngbe omo adie lo, o si ta eiye asa na nibon o si pa. Nigbati o pa tan, o si ri nomba kan ti nwon te si ara panu kekere kan ti nwon so mo lese, o si lo fi han ijoba.

Awon egbe kan ti a npe ni, Natural History Museum to wa ni Goteborg Sweden dahun pe tiwon ni eiyẹ na, eyiti Ugbagu pa nigbati o nse ode ni agbegbe Otuocha.

Eiyẹ na je awon eiye ode, ati wipe nomba ti nwon wi na je ti Museum Goteborg ni Sweden o si ni ila fisefun lorun re. Nse ni eiye na ya lo larin awon egbe re yoku

E ma polowo oja yin sinu iwe Irohin Eleti - Ofe

# Oro Sardauna to Awolowo lorun



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni Sardauna ti o dide lati Kaduna wa si Eko, o si mu Mohamed Ribadu danilo si Ibadan lati foju kan Awolowo nipa oro ilosiwaju ile Nigeria ore na si je eyiti inu Awolowo dun si tobe ti o duro ba awon alejo nla meji na ya aworan yi.

(Lati owo osi)

Oloye Rotimi Williams Oloye Awolowo, Sardauna Sokoto Oloye C.D. Akran ati Malam Mohamed Ribadu.

Ohun ti o fa sababi ipade yi ni igbe ti awon iwe irohin nke wipe ki awon Alakoso ijoba wa meteta se ipade po yanju edekoye kuro larin won, ki oro won le papo nilu Oyinbo

# Oriki Ile Yoruba

Oriki je oruko ijinle ti a fi npe eniken ti ori oluwa re yio fi wule, tobe ti ko fi ni mo igbati yio se ohun ti ko fe se. Olorun ona ni Oriki ti enia le fi ki, ti inu re yio dun ti yio si se ohun ti oluwa re fe fun u. Apere oriki Olorun ni Jebota oba ti igbe eda ke nsu, oba Inea, loni, ati titi laelae, Oba Ogbori-odo ja bi oji, Arabe nla kan ti o nse igbo kiji-kiji, obirinti, aji pe ojo iku da. Bi enia ba nki Olodumare le bi iru eyi lai ko fi okan pe okan. O daju pe oluwa re yio ri oju rere Olorun.

Awon ara Ikoyi ile, ati awon ara Ile Ijaiye ati awon ara ile Ogbomoso ni nwon nki ni Eso Ikoyi ilu miran wa ti owon nki ni Eso. Nigbati awon Oniraro tabi awon Onile gaogan ba nki awon omo Eso, gbogbo eniti iran re je ti Eso ni yio teti lele lati ma gbo ohun ti owon nwi, ori won a si ma wule nigbati owon ba bere si robin iru ise akikanju ti baba nla won ti se nigba kan, ori eni a ma wule tobe pelu awon elomiran a ma bu si ekun idunnu. Die ninu Oriki Eso niyi:- "Eso Ikoyi, omo agbonlona ti ko ori iku sa elegba a sun pelemo lojo ti a rogun oba, Eso rogun yo sese mote orun Eso Ikoyi ko nje Okete obinrin won lo nfi apa ewusa jeko, Eso Ikoyi mote orun, Siga ni ibi sa loju ogun si tabi Sige".

Awon ara ilu Offa nigba atijo je omo Oduduwa. Nigbati nwon si kuro ni ile Ife, nwon tedo sinu papa kan, ti a npe ni Offa papa ibe ni didi oba marun ti wa ja ko o'a kefa to ko won lo si Offa Esun. Nibin ni awon gbe ba ilu Erin ji'un. Ninu Oriki won ni a ti gbo wipe bi oro ba di oro gidigbo, ko si ilu kan ti o le fi ehin ara Offa bale. Die ninu awon oriki ara Offa ni wonyi "Olalomi, omo abise-joruko ijakadi ti oro Offa. Ija kan-ija kan ti nwon ja l'offa nile Olalomi nko? oju ta lose? o seju ebe, o seju poro ninu oko, ibo se oju oloko iba la won. Olofa omo lare ki o dogba, okan ko gbodo juka, loku jukan-bikan jukan ogun niko won reo yere arija-joro"

Iyawo eja ni o se,
Ma se ila o;
Eja ni o se;
Ma se ila.

# Dokita Jones D'ologbe

Dokita Curtis Crispin Adeniyi Jones agba, je eniti a bi, ti a si to dagba nilu Saro, ibe lo si koko bere eko re nigbati o ka iwe de wajalaline ni Saro, nigbana lo koja lo silu Oyinbo, o si lo ko eko ni Durham University, ibe lo ti gba awon oye nlanla wonyi M.B., B.S., ni odun 1901.

O lo darapo mo awon egbe Onisegun kan ti a npe ni West African Medical Service, ninu egbe yi ni awon ti yan a wipe, ki o wa lo sise nile Nigeria ni odun 1904. Nigbati o si kuro ninu awon egbe ti a wi tan ibe lo gbe ti da ile iwosan tire sile, o si nrise se geregere.

Ninu odun 1904 lo gbe iyawo wede, lasiko igba re ni ilu Eko o je okan pataki ninu awon Ogbon Eko tobe ti awon fi yan si igbimo Asofin ilu Eko, ni odun 1923. Bakanna ni nwon tun yan on gegebi Councillor ninu Igbimo Munisipe (Lagos Town Council).

Awon omo ati awon ebi re ni wonyi:- Iyawo Ologbe, Lizzie Adeniyi Jones, o di omo odun metadilogorin nisisiyi. Remi Doherty, ti o nse Iyawo Dokita Henry Doherty, Iyawo Tunde Adeniyi Williams, Iyawo Macgrath, Dokita Ade Adeniyi Jones ati Dokita Tunji Adeniyi Jones. Ologbe yi faiye sile ni 20th osu March 1957, nwon si se isin ikehin fun ninu Sosi Alagogo lehute Ehiwebeti (Christ Church Cathedral) nwon sinku re si Ikoyi.

# Ore Die Ota Die L'o Npani

(O bere loju ewe kini)

Se-dada, ki nwon si gbe si yara eto fun, o wa lo fi ogun majele sinu re, bi iyen ti wole ti o bu okele oba ti o si ni ki on fi sinu obe, ni ejo nla kan ba jade ninu obe ara ba fu Se-dada, o si so okele oba sile.

O wa mu aso lowo re to ba di oba iwonba ati erun sinu re o si gbe si apo ewu re, o san owo re, o jade si ibiti awon ero joko si ti nwon si nse awada. Nigbati o se o ni on nlo sile.

Aniyan Kotun nipe Se-dada ti je majele ati pe owo on ti te. O reti reti, ojo gori ojo, osu gori osu, nkankan ko se Se-dada. O wa ronu ona miran.

O tun di ole kan, o pe Se-dada o si ni on nfe ki o sin on lo si idale kekere kan, iyen si je ni ilo. Ki ojo to pe Kotun ti lo si ibe ... pose ijoko sile, o si tun fi ogun le ori ijoko kan sile fun Se-dada, o pada wa sile.

Ojo ti awon o lo pe, won de ibe won ki won ninu ile, ni Se-dada ba joko sori apoti kan eyiti Kotun rese sile fun ara re, ni ara ba nfu Kotun ko le joko mo, ni Se-dada ba ni ki o joko, o ko, nigbati oju ti, ti ori okan mu tan lo ba pe Se-dada ti o si nipe ki o darijì on, pe nkan bayibayi ni on ti se si, atipe gbogbo ona ti on gba lati fi se ni jamba ko besi, o si dobale fun gbalaja, osi ni lati oni lo on ko tun ni da'le re mo.

Se-dada ba dahun pe eniti Olorun nbukun ni on, ti eda si nbuku. Atipe eniti Olorun ko pa, eda kan ko le pa.

Lati igbana ni olukuluku ba gba ipin tire ti won si nlo lototo.

Itan yi ko wa pe ti a ba nba enia se ore, ki a fe tokantokan, ki a mase ba enia se ore die, ota die, iku lo nso pani o.

Ki Olorun gbe wa leke ore abinu-eni o. Amin.

Modupe Odutola,
66, Feleye St.
Ibadan.


## Kere o!

A ti ni oriširiši ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokuntin tohintin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Bamgbose Road, Lagos







Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 4337